# KRISTI BỌ́ ẸGBẸDỌGBỌN ENIYAN Ó SI RÌN LORI ÒKUN
## Matteu 14:13-36
### ẸKỌ 93 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Jesu si wá, o si sọ fun wọn wipe, Gbogbo agbara li ọrun ati li aiye li a fifun mi" (Matteu 28:18).**

**Ọpọ Eniyan Tẹle E**

Nigba ti Jesu gbọ nipa iku oró ti Johannu Baptisti ku, O fẹ dá nikan wà, nitori naa O bá ọkọ̀ rekọja Okun Galili lọ si ibi iju. Ki i ṣe pe Johannnu Baptisti jẹ ibatan Jesu nikan, ṣugbọn o ti kó ipa pataki kan ninu titan Ihinrere kalẹ. Oun ni iranṣẹ ti Ọlọrun rán lati tun ọna ṣe fun Jesu Kristi. O tako ẹ̀ṣẹ, paapaa ju lọ ni igbesi-aye ọba. O sọ otitọ nigba ti o wi pe kò tọ́ fun Hẹrọdu lati gba aya arakunrin rẹ̀. Nitori idi eyi ni a ṣe bẹ́ Johannu Baptisti lori.

Jesu ti n waasu, o si ti n wò ọpọ awọn eniyan sàn ṣugbọn pẹlu iroyin buburu nipa iku Johannu, O n fẹ isinmi. Ṣugbọn nigba ti O de eti okun, O ri ọpọ eniyan ti wọn ti n tẹle E. Kò si bi o ti le rẹ Jesu tabi ki ọwọ Rẹ̀ di tó, ki O má ran ẹnikẹni lọwọ. Oun kò dá awọn eniyan naa lẹkun lati tẹle E, bẹẹ ni ko sọ fun wọn lati fi ibẹ silẹ titi wọn fi ni itẹlọrun, ti wọn si yó. Nigba ti O ri awọn eniyan naa -- ẹgbẹẹdọgbọn (5,000) eniyan lai ka awọn obinrin ati awọn ọmọde – aanu wọn ṣe E, O si bẹrẹ si wò awọn olokunrun sàn.

**Itọju Awọn Alaini**

Nigba ti alẹ́ n lẹ lọ, awọn ọmọ-ẹyin Jesu wi fun Un pe ki O rán awọn eniyan naa lọ, ki wọn ba le lọ si ilu lati ra ounjẹ. Dipo ṣiṣe bẹẹ, Jesu wi fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe ki wọn bọ́ awọn eniyan naa, ṣugbọn akara marun-un ati ẹja meji pere ni gbogbo ounjẹ ti o wà lọwọ wọn. Sibẹ, a sọ fun awọn ọmọ-ẹyin pe ki wọn mú ounjẹ naa wá sọdọ Jesu.

Lọwọ Jesu, awọn ohun kékeré paapaa le di ibukun fun awọn ẹlomiran. Gẹgẹ bi akara marun-un ati ẹja meji ni ti kere pupọ lati bọ́ ijọ eniyan bẹẹ, bakan naa ni awa tikara wa kò le ṣe nnkan kan, ṣugbọn nigba ti a ba jọwọ ara wa fun Jesu, igbesi-ayé wa le di ohun elo fun iru iṣẹ iyanu bayii. Awọn ọmọ-ẹyin i ba ti wi pe iru nnkan kékèké bayii ko le tó lati bọ́ awọn eniyan naa. Boya o le ro pe talẹnti rẹ kere pupọ to bẹẹ ti wọn ko le wulo fun Ihinrere. Ṣugbọn ibaa jẹ talẹnti, akara ati ẹja, tabi ohun kekere miiran ti ko ni laari, Jesu le lo o lati mu ọla ati ogo wa fun ara Rẹ̀. Bi o tilẹ jẹ pe awọn ọmọ-ẹyin ṣiyemeji nitori ounjẹ ti o kere yii, wọn gbọran si Jesu lẹnu. Wọn ko mọ ohun ti Jesu yoo ṣe pato ṣugbọn wọn mọ pe O le ṣe ohun gbogbo. O n ṣe itọju, O si n ṣe aniyan fun awọn alaini sibẹ, O wò awọn olokunrun sàn, O si pese ounjẹ fun wọn lọna iyanu. Gẹgẹ bi O ti bọ́ awọn ti ebi n pa ni ọjọ wọnni bẹẹ ni O n bọ́ awọn ti ebi n pa nipa ti ẹmi lonii.

**Bibu Akara**

Bi ijọ eniyan ti jokoo lori koriko, Jesu mú ounjẹ naa, O si sure si i, boya gẹgẹ bi Onigbagbọ ti maa n gbadura pe ki Ọlọrun bù si ounjẹ rẹ̀ ki o to jẹun. Nigba naa ni Jesu bu ounjẹ naa si wẹ́wẹ́, O si fi fun awọn ọmọ-ẹyin, wọn gba akara ati ẹja naa lọwọ Rẹ̀, wọn si fi i fun awọn eniyan.

Ni ọjọ naa awọn ọmọ-ẹyin fun awọn eniyan ni ounjẹ ti ara, ṣugbọn ni ọjọ iwaju, wọn fun awọn eniyan ni ounjẹ ti ẹmi, nitori a pè wọ́n lati waasu Ihinrere. Wọn gba ounjẹ ti ara ati ti ẹmi lati ọdọ Jesu. "Ni yiyara nyin kuro lọdọ mi, ẹ ko le ṣe ohun kan" (Johannu 15:5). A kà ninu Johannu 1:14 pe "Ọ̀rọ na si di ara, on si mba wa gbé," ati ninu Johannu 6:48; Jesu wi pe, "Emi li onjẹ ìye." Nigba ti a ba n sọrọ nipa ounjẹ ti ẹmi, a n sọ nipa Bibeli, tabi Ọrọ Ọlọrun. Nigba pupọ nigba ti a bá n gbadura a n bẹ Oluwa lati bukun Ọrọ naa, ati lati bukun ẹni ti o n waasu Ọrọ Iye naa fun wa pẹlu – alufaa ti n kà lati inu Bibeli ti o si n fi ounjẹ ẹmi bọ́ ọkàn awọn eniyan.

**Ni Ọpọlọpọ**

Lẹyin ti Jesu sure si ounjẹ naa tan, O tó fun gbogbo eniyan, o si tun ṣẹ́kù pẹlu. A sọ akara marun-un ati ẹja meji di pupọ. Bẹẹ gẹgẹ ni ounjẹ ẹmi rí -- ọpọlọpọ rẹ̀ ni o wà ninu Bibeli fun gbogbo eniyan ati fun gbogbo akoko. Ninu rẹ̀ ni a n ri ohun ti a ṣe alaini, ti o si tun ṣẹku fun igbà miiran pẹlu. Ounjẹ ẹmi ki i tán.

**O Nikan Gbadura**

Nigba ti awọn eniyan naa lọ tan, Jesu ran awọn ọmọ-ẹyin lọ ṣiwaju Rẹ̀ si odi keji okun. O fi apẹẹrẹ lelẹ nihin fun wa lati maa dá nikan gbadura. Bi Jesu, Ọmọ Ọlọrun, ba ri aini Rẹ̀ fun adura, bawo ni aini awa naa ti pọ to lati nikan wà pẹlu Ọlọrun ninu adura?

Ki i ṣe igba ti Jesu ba ni iwuwo ọkàn nikan ni O maa n gbadura. Ni igba pupọ, ati ni oriṣiriṣi akoko loojọ ni Jesu maa n gbadura. Nigba miiran Oun nikan maa n dá gbadura; nigba miiran awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ maa n wà ni tosi. "O si dide li owurọ̀ ki ilẹ to mọ́, o si jade lọ si bi iju kan, nibẹ li o si ngbadura" (Marku 1:35). "Ọ̀pọ ijọ enia si jumọ pade lati gbọ́ ọ̀rọ rẹ̀, ati lati gbà dida ara lọdọ rẹ̀ kuro lọwọ ailera wọn. O si yẹra si ijù, o si gbadura" (Luku 5:15, 16). "O si ṣe ni ijọ wọnni, o lọ si ori òke lọ igbadura, o si fi gbogbo oru na gbadura si Ọlọrun" (Luku 6:12). Ni igba miiran Jesu gbadura nigba ti ọpọ eniyan wà yi I ká. Nigba ti a ri I bọmi O gbadura (Luku 3:21). Nigba ti O duro leti iboji Lasaru, O gbadura (Johannu 11:41).

Ki i ṣe igba gbogbo ni Onigbagbọ le lọ si ibi kan fun ara rẹ̀ lati gbadura, ṣugbọn lati inu odo ọkàn rẹ̀ ni oun ti maa n mí èmí adura. Nigba pupọ loojọ, ni ibi iṣẹ, ni ile iwe, tabi ni ibikibi ti o ba wà, Onigbagbọ maa n wo Ọlọrun ki i ṣe fun iranlọwọ tabi itọni nikan, ṣugbọn oun maa n fi iyin ati ọpẹ fun Ọlọrun pẹlu. Ni igba miiran, oun nikan gbadura, ni igba miiran ẹwẹ, oun a gbadura nigba ti ọpọ eniyan bá wà pẹlu rẹ̀. Igba meloo ni iwọ maa n gbadura?

**Afẹfẹ N Gba Wọn Kiri**

Bi awọn ọmọ-ẹyin ti n kọja okun, iji dide, igbi si n ti ọkọ̀ naa siwa sẹyin. Jesu mọ pe wọn wà ninu ewu, nitori naa O lọ bá wọn. Bakan naa, lọjọ oni, ni Oun mọ igba ti awọn eniyan Rẹ̀ n fẹ iranwọ Rẹ̀, Jesu si wà nibẹ lati ràn wọ́n lọwọ.

Ni akoko miiran, nigba ti awọn ọmọ-ẹyin n rekọja Okun Galili si ilẹ awọn ara Gadara (Marku 4:35-41), ìji dide si wọn. Jesu sùn ninu ọkọ̀ ni akoko naa. Nigba ti wọn pe E, O dide, O si bá afẹfẹ wí. Ẹnu ya wọn si agbara ti Jesu ní, ṣugbọn, sibẹ, wọn ko ti i mọ pe ti Rẹ̀ ni gbogbo agbara ni Ọrun ati ni aye (Matteu 28:18). Ni akoko yii bi Jesu ti n rìn lori omi, ti O súnmọ ọkọ ti afẹfẹ n ti siwa ti sẹyin yii, ẹru ba awọn ọmọ-ẹyin nitori wọn kò mọ pe Oun ni.

**Tujuka**

Igba kan le wà ni igbesi-ayé eniyan nigba ti ẹ̀ru yoo bà á, nitori kò mọ pe Jesu wà nitosi. Ko yẹ ki awọn ọmọ-ẹyin bẹru rara, nitori Jesu wa nibẹ lati ràn wọn lọwọ. Lọjọ oni, Jesu wa nitosi lati ran wa lọwọ, nitori naa kò yẹ ki Onigbagbọ bẹru nigba ti afẹfẹ bá ṣe ọwọ́ odi si i, ti ohun gbogbo ba si darú.

Jesu sọrọ itunu ati ikiya si awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀. O fi ara Rẹ̀ han wọn, O si wi fun wọn pe ki wọn má bẹ̀ru. Oriṣiriṣi ibẹru ni ó wà. A maa n ni ibẹru ti ẹni iwa-bi-Ọlọrun, ki a má ba ṣẹ tabi sọ ohun ti inu Ọlọrun kò dùn si, ṣugbọn ibẹru miiran ni awọn ọmọ-ẹyin ni. Wọn ni ibẹru ti ara ni ti ohun ti wọn rò pe yoo ṣẹlẹ si wọn. Jesu sọ fun wọn pe ki wọn ma bẹ̀ru.

**Wo Jesu**

Nigba ti wọn mọ̀ pe Jesu ni, Peteru fẹ́ tọ Ọ lọ, ki o si ṣe gẹgẹ bi Oun ti ṣe. Jesu wi fun un pe ki o maa bọ̀; nitori naa Peteru jade kuro ninu ọkọ, o si bẹrẹ si i rin lori omi lati tọ̀ Jesu wá. Niwọn igba ti Peteru tẹju mọ́ Jesu, o n rin lori omi, nitori Jesu ran an lọwọ; ṣugbọn gẹrẹ ti o wo iji, ẹru bà a o si bẹrẹ si i rì. A mọ pe kò si ẹni ti o le rin lori omi funra rẹ̀. Ṣugbọn Jesu fẹ fihan awọn ọmọ-ẹyin ati awa naa pẹlu, pe gbogbo agbara ni ti Rẹ̀. O fẹ fihan pe eniyan ko le ṣe ohun kan lai si Oun. Ki i ṣe iṣẹ iyanu nikan ni Jesu tikara Rẹ̀ le ṣe, ṣugbọn Oun yoo ran awọn miiran lọwọ lati gbé igbesi-ayé bi ti Rẹ̀, ati lati maa ṣe gẹgẹ bi Oun ti maa n ṣe.

Jesu n pe olukuluku eniyan lati wá sọdọ Rẹ̀ ati lati ṣe gẹgẹ bi Oun ti n ṣe. Jesu gbé igbesi-ayé ti kò lẹṣẹ, Onigbagbọ si maa n gbe igbesi-ayé ailẹṣẹ, gẹgẹ bi Jesu ti ṣe. Kò si ẹni ti o le ṣe e ninu ipá ti rẹ̀ ṣugbọn Jesu ni O n fun ni ni agbara lati gbé igbesi-ayé ti ko lẹṣẹ. Ṣugbọn bi oluwarẹ ba mu oju kuro lara Jesu, oun yoo sọ agbara naa nù. gẹgẹ bi Peteru ti ṣe. Bawo ni o ti ṣe pataki tó fun Onigbagbọ lati tẹju mọ Jesu, Olupilẹṣẹ ati Alaṣepe igbagbọ rẹ̀ (Heberu 12:2).

Nigba gbogbo ni Satani, ọta wa ẹmi maa n fẹ tan wa jẹ lati mu oju wa kuro lara Oluwa. Eṣu mọ̀ pé nigba naa ni a o bẹ̀ru, ti a o si bẹrẹ si rì sinu ẹ̀ṣẹ. A gbọdọ ṣọra nipa ohun ti oju wa n wò.

Bibeli sọ fun wa nipa Adamu ati Efa, ti wọn n gbe ninu Ọgbà Edẹni ti o dara pupọ, eso wa nibẹ fun wọn lati jẹ, afi eso igi kan ti wọn kò gbọdọ fọwọ kàn. Ṣugbọn nigba ti Efa ri i pe igi naa dara fun ounjẹ, nigba naa ni o

ṣe aigbọran si Ọlọrun o si jẹ eso naa (Gẹnẹsisi 3:6). A jẹ wọn niya, wọn ko si tun le gbe ninu Ọgbà naa mọ́. Njẹ iwọ ri ohun ti o ṣẹlẹ nigba ti o WO igi naa?

Ni akoko kan, ọkan ninu awọn Ọmọ Israẹli, ti a n pe ni Akani, ṣe aigbọran si Ọlọrun, o si mu awọn aṣọ diẹ ati fadaka ati wura. O wi pe nigba ti oun RÍ awọn nnkan wọnni wọn wu oun, nigba naa ni oun si mu wọn (Joṣua 7:21). A jẹ ẹ niya nitori ẹ̀ṣẹ rẹ̀. Ki gbogbo eniyan kọ́ ẹkọ lara awọn eniyan wọnyii, ki wọn si tẹju mọ Oluwa, ki wọn má ṣe wo awọn ohun aye ti yoo dí igbagbọ wọn lọwọ, ti yoo si mu wọn sọ iriri wọn pẹlu Ọlọrun nù.

Nigba ti Peteru mọ pe oun n rì, o kigbe pe Jesu lati ran oun lọwọ. Loju kan naa ni Jesu na ọwọ Rẹ jade, O si yọ Peteru. Bakan naa ni o ri lonii: nigba ti ẹni kan ba mọ pe oun n rì sinu ẹ̀ṣẹ, oun yoo si ṣègbé, bi o ba kigbe pe Jesu lati gba a, Jesu wa nibẹ lati gbe e dide loju kan naa. Ki i ṣe Peteru nikan ni Jesu yọ, ṣugbọn O mu ki afẹfẹ duro pẹlu. Awọn ọmọ-ẹyin fi ori balẹ fun Un. Bayi ni Onigbagbọ maa n ṣe nigba ti Jesu ba gba ọkàn rẹ̀ là ti O si mu ki igbi iyemeji duro.

Nigba ti wọn de odi keji okun wọn ri awọn eniyan ti wọn ni igbagbọ. Ọpọ awọn olokunrun ri iwosàn; gbogbo awọn ti o si fọwọ kan Jesu ni a wosan patapata. Awọn ti wọn ni aisan ninu ara ati ninu ẹmi yoo ri iwosan nigba ti wọn ba fi igbagbọ wá, ti wọn si jọwọ ọkàn wọn fun Jesu.

**AWỌN IBEERE**

1. Ta ni Johannu Baptisti?
2. Ki ni ṣe ti wọn pa á?
3. Meloo ni ijọ eniyan naa?
4. Bawo ni a ṣe bọ́ wọn?
5. Ki ni ṣe ti Jesu fẹ dá nikan wà?
6. Ki ni ṣe ti Peteru rì sinu omi?
7. Bawo ni a ṣe yọ Peteru ti ko ri sinu omi?